# ALAFIN QYQ YIO LQ SE ATIPO NI ILORIN

**Ikede**

Aso ikede yi f u n gbogbo enyin Onkawe wa ati asoju wa wipe, eni kni ti owo ba teko si owo re ki o tete fi ranse nitori gbogbo ohun elo ti a fi ntewe irohin lo ti gbe owo leri.

Enikeni ti ko ba fi tire ranse so da iwe re duro ao si so agbara lati gba owo wa ni owo re. Olotu.

ELETI OFE

A-NJU-WON KO SE WI-L'EJO

**Ikede**

A nfe awon asoju fun iwe Irohin Eleti Ofe kakiri ile Yoruba gegebi Iloro Ilori, Ilo, Papa-Lanto Wasimi Ogeji, Olorunmeji, Ikenne, Odogbolu, Ilaro, Iwo, Ikirun Ede, ati Modakeke.

E kowe si Editor Eleti Ofe 62 Kosoko Street Lagos.
P.O Box 467

VOL VII No. 380 LAGOS (SATURDAY) QJQ ABAMETA SEPTEMBER 11, 1954. IYE OWO ELETI QPE KQBO MEJI (2)

## Alafin Qyo Yio Lo Se Atipo Ni Ilorin

**Ibadan** Ajele Agba ati Kekere so fun Alafin Qyo wipe bi o ba nfe alafia fun awon enia re ati awon ara ilu re, ki o yara jade ni kiakia kuro nilu Qyo ki o si lo se atipo ni Ile Ife, ki o se gegebi Qba Alake ti se nigbati awon enia re dide si, ti ko jeki o di ijagboro ki o to sa jade.

Alafin dahun wipe, eru koba on lati jade kuro nilu sugbon niti wipe ki on wa lo si Ile Ife yen, rara, on ko ni lo si Ife, o kuku ro on lorun lati lo si Ilorin, nitoripe ibe je ilu awon Muselumi, esin kanna ni nwon je pelu on.

A gbo wipe awon awujo Minister se ipade apero lori awon ijogbon ti o nsele nilu Oyo, nwon si fenu sokan kowe si Gomina Eko wipe ki o yan enia kan wa lati wa se iwadi kini ohun ti o fa rogbodiyan ti odun 1953 ati 1954 yi wa.

Gomina si yan Ogbeni agbejoro ijoba ti a npe ni R D Lloyd lati lo se iwadi oro na asoju Gomina ti Ibadan si sekede nilu Oyo wipe, ki olukuluku enia lo si medo joko je, titi on yio fi pari iwadi oro. Nitoripe ijagboro ti o sele ni Oyo ie idagiri fun gbogbo enia, awon olopa si nsise won lati se iwadi awon to da rogbodiyan sile.

Awon enia ti olopa mu latari ijagboro to sele yi fere le ni adota enia, adajo Adesigbin n yio dajo lori won.

**CHAIRS**
FOR
**RENT**
APPLY OFE
3, Aibu Street
**LAGOS**

## THE NATIONAL BANK
OF NIGERIA LIMITED.

ILE IFI OWO PAMQ SI TI ENIA DUDU TI O ni ese nile.
Ni gbogbo agbaiye ni angbo oruko re.
Iranlowo ni o je fun gbogbo enia dudu.
O nse itoju owo awon Agbe.

**ILE ISE WA NI EKO :-**

37, MARINA P. O. BOX 508 LAGOS

AWON ASOJU WA NILU OBA NIYI

THE NATIONAL PROVINCIAL BANK
(Overseas Branch)
1, PRINCESS STREET LONDON E. C. 2.

THE COMPTOIR NATIONAL DESCOMPTE DE PARIS
8\13, KING WILLIAMS STREET, LONDON E. G.4.

## Itan Omo Oro Tabi Omo Alapapo

Iru awon omo bayi ti nwa si aiye lorisirisi igba, orisirisi si ni awon omo oro nwonyi, Omiran je olori meji ara kan ati ese meji. Omiran je eyiti o li ori meji, ara meji ati ese meji ototo, sugbon ejika won so po mo ara won.

Nigba aiye Are Qnakakanfo nile Ijaiye, li odun 1816, a gbo wipe obinrin kan bi omo oro bayi awon npe obinrin na ni Akirinola Ato. Qmo meta ni obinrin na bi, o bi eyoka loto, o si bi awon meji ti o ku ni asopo. Nwon ni ori lototo, ese ati apa li ototo, sugbon ninu agbedun kanna ni nwon njeun si.

Gegebi o si ti je wipe, ninu asa ile Yoruba, oba omo ni nwon ka omo Ibeta si, Are pase wipe ki a gbe awon omo na lo fihan Alafin okan soso lo pada wa sile Ijaiye ninu awon omo Ibeta na. O si tun se li asiko Bale Foko obinrin kan ti a npe ni Laduntan biomo oro ni Oke Offa, omo na je olori meji ara kan ati ese meji. Aworan eyiy mbe lati fi han enikeni ni ilo ise iwe irohin Eleti Qfe ni, 62 Kosoko Street. Lagos.

sugbon idi re ti a fi npe iru awon omo be ni Siamese ni ede oyinbo ni wipe lapa ilu oyinbo lohun ilu ti a koko gburo iru awon omo be ni ilu Siam lodun 1811. Ijoba pase wipe ki a fi awon omo abami yi sile, nigbati nwon dagba, iya won bere si fi nwon gba owo kiri. Nigbati o di odun 1874 okan ninu awon omo abami yi salaisi, ekeji wa ranse pe Dokita lati wa ya on si oto, ki Dokita to de, ekeji papaa na gbera o gba orun lo.

## Eko Fun Awon Qmo Ile Eko Giga

ST ALBANS je okan ninu awon omwasu to nwasu oro Olorun fun awon Gesi laseko ti awon Aguda njoba lori won.

JOHN WYCLIFFE li enit o koko daba lati se itumo oro Bibeli si ede Gesi ni odun 1378.

CHRISTOPHER COLUMBUS ni aririn-ajo loju omi ti o koko de ilu Bahamas lodun 1492. O je omo Aruda on na lo si koko je ajeji ti de Ile Amerika lodun 1502 lodun na lo si ku silu Valadolid.

Vasco Da Gama ara ilu Potogi lo koko gbe oko re koja ni ogegoro Cape of Good Hope, lodun 1498. William Caxton ni omo ilu Gesi ti o koko da ise ero itewe sile lodun 1476. Sir Francis Drake ni oga oko Gesi kan ti o koko fi oko re yi aiye ka lodun 1579. Martin Luther je okan n'nu awon elesin igbagbo ti o koko ri opolopo asise ti awon Aguda ti se sinu iwe Bibeli Nigbati Pope nilu Aguda gburo iru ise ti o se, o yo o kuro larin ijo, sugbon Luther ja fun ara re, o si gba ara re sile ki o to ku ni odun 1546.

Sir Cristopher Wren je okunrin Olola kan nilu Gesi on ni enit o ko opolopo awon ile nlanla nilu oyinbo, on li o si ko ile isin St. Paul's Cathedral nigboro ilu London

## OHUN TI O TUN SELE LEHIN IJAGBORO QYQ

**Oyo** Ohun ti a tun gbo wipe o sele lehin ija igboro ilu Oyo ni wipe nigbati ija na koko sele enia merin ni owo olopa te ninu awon omo egbe Oyo parapo ati N.C.N.C. sugbon lojo 8th osu Sep 1954, o di ogbon enia ti owo olopa ba ninu awon adarugudu sile nwonyi awon adaluru.

Ejo ti ijoba nfe ba awon enia nwonyi ro ni wipe nwon pa enia Nwon dano sun ile, nwon si da rogbodiyan sile.

# ELETI QFE

A-NDU-WON KO SE WI L'EJO

EDITORIAL OFFICE & WORKS — CABLES & TELEGRAMS

62, Kosoko Street, Lagos — "ETI-QFE LAGOS"

P. O. Box 467 — Phone 23370

VOL VII NO. 280 LAGOS, SATURDAY SEP 11 1954.


## Ija Ko Di Ola

Ani seni lojo lati gbo irohin nipa ijagboro kan ti o be sile ni ilu Ovo li ose to koja lo yi, ija na gbile tobe ge ti o ti je wipe, odidi enia mefa lo fi emi won sofo danu, beni ogunlogo enia lo si fi ara sese. Kinla! Ototo eyi ni ano igbin, igbin ku ikarawun ko sokun. Bawo lo se to wipe ki a ma pa ara wa nigbati o je wipe omo ku aro, o ko jire kanna ni gbogbo wa je, papaa nigbati a nmura lati gbara wa kuro ni oko eru.

Lotito, ni a ti gbo wipe, ko nse oju boro ni a fi ngba nmo lowo ekuro, iyen ni wipe ko si ilu kan ti o le fi oju boro gba ominira, sugbon bakanna ni enikan ko ni le fi ara mo ominira, ti yio mu iku dani tabi eyiti yio mu airoju dani, iru eyini ko nse ominira rara.

A fi ilede wa ti ose yi be awon janduku enia nwonyi, awon aritc-ninu-idaru wipe, ki nwon mu suru nitorpe ete awo ni ete ogberi. Gbogbo ohun ti ijoba le yoruba nse ni gbogbo awon ilu yoku nwo se.

Oro Iselu ko ni lati ma ija dani, bi o ba je wipe awon enikan ni Oluwa fun ni agbara nisisiyi lati je olotu fun wa, e je ki a gbaraku ti won lehin, boya omo tire, obakan tabi iyekan tire ni ipo na yio kan lehin wa ola. Nitorina ija ko di ola, ohun ti suru ba se ti, ohun adiro ni yio gbe. Oro die to fun omoluwabi.


## Enjoy Your Own Songs

SUNG BY YOUR OWN PEOPLE IN THE WAY YOU LOVE. MASTERLY RENDERINGS OF TRADITIONAL AFRICAN MUSIC IS YOURS ON




OBTAINABLE FROM:

**The Association Of Nigerian Gramophone Dealers**

THROUGHOUT NIGERIA



## WANTED

Wanted immediately 2 Lady Clerks with Quran knowledge and simple English. Salary liberal

Apply to MR B. O. SALMAN

15, Holloway Street

LAGOS


## Iye Qmo Ti A Bi

**Eko** Iye awon omo ti a bi nigboro ile Eko larin ose kan to pari lojo 3rd osu Sept. 1954 je 278.

Sugbon iye awon enia ti o salaisi lose na je 86.


## Imoran Fun Eyin Abiyamo

Eyin abiyamo (ya ra) **'Omorela'** O dara pupo fun awon omode

A ma je ki omode ti orun sun daradara, o dara fun osuto, Iko ati orisirisi arun miran ti o ma aba omode ja si asiko ehin. Opolopo abiyamo lo ti lo egbogi yi fun omo won ti won si so wipe o dara pupo fun awon omode.

**Omorela Baby Mixture**

SILE MEJI ABO (2/6d) FUN IGO KAN

wa ipde

**Commercial Medicine Stores**

QUALIFIED CHEMIST

13, Victoria Street LAGOS.




# SIMENTI TI OYINBO

# BURHAM PORTLAD CEMENT

## NI A FI PO

## KONKERE TI O LE JULO

BURHAM BRICK LIME AND CEMENT Co.
BURHAM WORKS
TRADE
PORTLAND CEMENT
MARK
– LONDON –

Konkere ti a ba fi Simenti ti oyinbo

Burham po, yio le gbonin-gbonin

titi aiye. Eniti o se Simenti Burham Portland

ni okiki kakiri agbaiye. Bakanna ni Simenti re si je

ojulowo ni gbogbo igba On ni a fi ko awon ile

nla-nla nile Nigeria, lati iwon adota odun sehin.

## RA ODODO SIMENTI TI OYINBO

# BURHAM PORTLAND CEMENT


## Ikomo Larinrin Ni Oke-Okun

**Odua** Alagba wa Joseph F. Osadipo lo se komo jade omo re nile yi, ti o si fere je wipe ese gbogbo omo Yoruba lo peju sibi ase ikomo no.

Lojo na, oibi ase ikomo yi, won ni S. Tayewo, I. Durenigbati oju pe ti ese pe, Ogbeni toye, S. Akinyemi, M. Amoo John Lala lo fi iwe Orin Dafidi D. B. Akinrinola, Z. Oyeniran ni kika si ipade na, lehin na Z. Fakunle, J. Atoyebi, D. ni Ogbeni J. Akintola so omo O. Ajala, M. Adeniji, ati na ni oruko yi, Juliana Olufun-Iyefia Matemilowo ati Ige. milayo, J. Oyegbile lo si gbadura-Olorun ko wo omo na ju ia. Alaga ojo na ni Alaga tiwa lo, David

Iya Ikoko tape si pon oti, o si fi ona roka olukuluke enia nje, nwon si umu, Die nise awon enia ti a niran oruko

# Kini Awon Onkawe Wa Nro

## Tani Inu Re Yio Dun Ju

Oloto,

Gba mi laye lati se abere oiogbon si lodo awon okawe re ibere ni miyi wipe

Okunrin kan ni Wura lowo o nfe lati ta u ki o le fi owo re se ohun pataki kan ti o ti mbe lokan re sugbon ko ri enia ti o nfe Wura lati ra.

Ewe, okunrin kan gba owo lowo awa wura kakiri lati ra, ki o le fi se ohun pataki kan ti o nfe se sugbon ko ri wura ra rara.

Laifa oro gun, awon gbuto ara won okiai dide, ekeji dide, awon owa ara won lo, awon si pade enisi o fe ra, ati Eniti o fe ta si ta.

Nisn awon mejeji owonyi tani inu re dun ju?

Emi ni
Y.A. Agbaje
Ara Kumasi

## Idahun Si Ibere Lemomu Ajakuta

Oloto,

Gba mi laiye lati dahun si ibere Lemomu Ajakuta. Ibiti Olorun gbo se pe ki a ma pe Olugbala ni Jesu. Iwe Ihinrere Luke 1 26–35.

Itumo Jesu ni Olugbala, Itumo Emanuel ni wipe Olorun mbe pelu mi. Osigbagbo jeri pe Omo Olorun ni Jesu ninu Ihinrere John 3. 16.

Olorun jeri pe omo Olorun ni Jesu nse Matt 3, 17, oko 17 1.

Emi ni
C. O. Fagbore
ara Ebute Meta

## Owe Niyi Tabi Ayajo Ofo

Oloto,

Awon Ologbon papo lo nka iwe irohin re, mo si fe ki nwon la ye mi, yala owe ni oro yi tabi ofo.

Piri ni Olongo oji, a ko mba Olokunrun oyo li ori ite ko ju bayi lo.

Alafa Sodipe
Baba Keti

## Kini Itumo Owe Yi

Oloto,

Jowo, emo bakanna ni emi ako ni mo itumo awon ohun ti mo ngbo. Inu yio dun bi mo ba le ri eniti yio se itumo oro yi fun mi

Ekun iwaju niti ohin wo sare Kini itumo owe na,

Emi ni
Malam Shodipo
ara Oshodi

## SECOND HAND CLOTHING

| | |
|---|---|
| Women's long Coats | 2/- |
| Women's Short Coats | 1/- |
| Women's Dresses & Frocks | 1/- |
| Women's Shirts | 1/- |
| Costumes | 5/- |
| Men's Raincoats | 3/- |
| Men's Jackets | 1/-6d |
| Men's Waistcoats | 6d |
| Men's Felt Hats | 1/-6d |
| Men's Khaki Greatcoats | 20/- |
| Men's Ex-Service Overcoats | 10/- |
| Men's Overcoats-Civilian | 5/- |
| R. A. F. New Side Caps | 1/- |
| Men's Suits | 20/- |
| Ex-Army Blankets | 1/-6d |

No less than 250 supplied.
We have also Radiograms £10: 0s 0d
Secondhand Pianos £10: 0s. 0d.
Organs £10: 0s: 0d
Prices quoted ex-warehouse.
C.I.F. charges extra. Immediate attention. Write for full price list. Enquiries invited.

**H. NEWMAN & Co (MERCHANTS) LTD.**
88/92 Elizabeth Street,
Manchester, 8. England.
Cables: "Recovery" Manchester.

## REAL OPPORTUNITY FOR TRADERS

"Iron-Sheets, Cement, Stockfish
All kinds of Beer, Gin, Salt 40 lbs, Large Sweet mineral Waters, Flour, 100 lbs, Caustic Soda, Stout Beer.
Buy the Medicines:
Jedijedi and Inaren Bitter Tonics, Pile Tablets, Cough Mixtures, Tonics, Quinine Mixture, Metatone Eye drops, Earache drops, Toothache drops, Worm Expeller

**ASTHMA CIGARETTE**

This is good for asthma Bronchitis, Wooping Cough & Shortness of Breath etc, etc.
While assuring you of all our best attention at all times,
Buy the cheapest and Best articles and Medicine from :-

**J. A. AJAO BROTHERS**
10, Egerton Road, P. O. Box 358
Lagos, Nigeria

## NOW, AVAILABLE

BUGLES, BEDSTEADS
PAINTS DISTEMPERS
JAPES Etc.
Just write, Call, or
Phone 21372

**IKORODU TRADING COMPANY**
20/28, Balogun Street,
(P. O. Box 393) Lagos.
AND
NEW COURT ROAD
IBADAN

**Always Read And Advertise In Eleti Ofe**

## WANTED AGENTS

Agents & Stockists are wanted for selling our Chrome Leather Shoes Ladies, Sandals Ladies Purses on a salary of 300/- 8h. per month in every city and town. Full range of samples and agency forms can be had against £ 5/- in advance by British Postal Orders.

**INDO BRITISH COMPANY**
P. B. No. 1199, Delhi-6 INDIA

## INUA GOMBE PE GREGORY LEJO SI KOTU

**Eko** Ogbeni Hausa kan ti a npe ni Inua-Gombe enit eyinbo ti o npe ni Gregory fi ejo kan ti a npe ni Gregory fi aja re buje eniti ko dara li ojo na ni dojo Kotu, agbara gbaba, nwon ni ti eyinbo te ese. Pupa mododgbon aitoju o jo!

Nigbati Hausa na sese ne dide lati ba eyinbo na eja wipe ki adajo jowo ke on gba owo ogbeta Poun £500 lowo eyinbo na fun aja ti o fi bu oun je ni Ikoyi ni ojo 22nd osu May 1954. Nwon koiti da ejo o si owon o lere aja na.

My driving force

# OVALTINE




As a nourishing, sustaining snack, try "Ovaltine" biscuits. They are light, crunchy and crisp, full of the same traditional energy-giving qualities as "Ovaltine" itself.

'Ovaltine' goes with me on every long trip —it helps me keep strong and alert.

**Builds-up Nerve Strength Reserve**

OWA 174

## Iwora

Nigbati ara enia ba nfe gan Ohun ti o nfa a ni wipe nigbati Kidinrin enia ko ba sişe daradara mọ, iwora yi ni ikilo fun oluwa rę lati mọ wipe Kidinrin ko şişe to nitorina o wa nbę ti enia ba nlo egbogi yi yio ri alafia.

Ohun pataki ti o fa amodi wa fun enia ni wipe idoti pọ ninu ẹjẹ oluwa rę, lọ dan egbogi De Witt wo fun ra rę o le jo ohun ti o nfę lọ ra ọkan wo ninu şọbu egbogi.



Ohun to da wa loju ni wipe egbogi DE WITT'S PILLS je Eyiti a şe tenitoni, ohun elo rę egbo le si mọ.

DE WITT'S PILLS
for Kidney and Bladder Troubles


## Hrije Ninu Idaru N.C.N.C.

Awọn ęgbẹ kan wa ti a ko ba ma pe ni Arijẹ-ninu-idaru, Iwa awọn ọmọ ęgbẹ yi ni lati ma tan awọn enia je nwọn a si ma pa oniyiriyi irọ pẹlu ọnu didun fun awọn ti awọn ntanjẹ lati le fi gba nkan rere oniyebiye lọwọ wọn.

Ko sọe ẹnu didun nikan sọrọ ni nwọn o ma lo, şugbọn tọwtọsọ won ni nwọn o ma lo pelu, tọsan toru ni wọn o si fi ma para ọdọ oluwa rẹ niteri ki ọwọ wọn le tẹ ohun ti nwọn nfe. Bi ọwọ wọn ba ti tẹ ohun ti nwọn nfe. Kelekele ni nwọn o yẹra fun oluwa rẹ Irú iwa bayi ni a npe ni Alaimọre tabi Arijẹ-ninu-idaru.

Laisi tabi-tabi ẹnikẹni le jẹri pe ẹgbẹ N.C.N C ko şe ohun ti o tẹ awọn ara ilu Eko lọrun laseko ti nwọn nşelu Eko

Owo awon agba sọ bayi wipe' şaiti a fẹbin ti wipe bi a mu didu ọran gologoin lo fun ni ma Ęgbe N C N C ko şe ore kan fun ilu wa a jeki a kọ wọn silẹ ki a si fara mọ ẹgbe Afenifere nitoripe ina Bulai ko ajo ni aigba meji.

Şe ẹnyin papaa mọ Ogbeni Adeleke Adedoyin ti o fi gbogbo ara jiẹ fun ẹgbe na, aja ere kili rigba, nigbati o ri wipe Owijibiti ni wọn lo ba kuro larin wọn ti o si pada di ọkan ninu awọn O gbogi lẹhin ẹgbe Afenifere


# Dokita Fihan Wipe

## Ose Palmolive Le Jeki Oju Re Dara
LARIN OJO MERINLA



Ara mi jolo o tun jide Nisisiyi ti mo tele ilana

Palmolive

Iba ohun ti iwo yio se nivi
1 Fi ose Palmolive we oju
2 Fi hiho pa oju fun isẹju kan.
3 Fi nso nu kuro se he nigba meta lojumọ fun ojo merinla.




EPO ILE AFRIKA
NI A FI SE OSE YI

COLGATE PALMOLIVE LO SE


## Sokesodo Kan Fi Ara Gbalumo Lode Oyo

Oyo Irohin kan wa wipe lasiko ti awọn ẹgbe Afenifere aşe ikede fun ọmọ ẹgbe wọn nigbore Oyọ, ti ọse gbogbo awọn ijoye ẹgbe na pe a be, a gbọ wipe ọkunrin ko şeku ko şeyẹ kan le ba ọkan ninu awọn ijoye ẹgbe na şeru.

Nigbati awọn ọmọkunrin na ri awọn fere fi ilu pa lori, Awọn ẹgbe Afenifere dide lati gba ọkunrin na, ibe ni ijagboro gba ti be sile larin ẹgbe Afenifere, Ọyọ Parapọ ati N. C. N. C,

Şugbọn ọkunrin na papaa to da rukerude yi sile ti salọ. Ọpọlọpọ enia lo fi ara gbogbọ eyi nikan ọ, lẹhin ti eyi sele tan, awọn tun bere si jeja kakiri ilu. Awọn Ọyọ Parapọ ati ẹgbe N. C. N. C. lo şẹẹ na. Ayafi igbati awọn Ọlọpa yiobọn pamọlekun ni rogbodiyan na to rọle.

Oloye H. O, Davies ọkan ninu awọn ọmọ ẹgbe N. C. N. C, wa nibi rogbodiyan yi.




## Awon Ti O Lo Sare Ije Gba Iyi Bo Wale

**Eko** Awon enia mokanla ninu omo ilu Nigeria ti o we okun, we ose lo s'ilu Canada lati lo ba awon oyinbo ta peru sre s'se awon enia na nigbanyi. E. A. Ajado, E. Ifejuma, o gba eye golu wa sile, A. K. Amu, M. A. Arogundade, P. Ejiri, gba eye Fadaka wa sile N. B. Osagie. Garuba Ide gba eye Baba wa sile, T. A. Erinle igbakeji Capt. Ado Garuba, abese kun bi ojo, H. J. Eperigie, asoje Manager, J. Fansworth, S. O. Williams, K. A. B. Olowu, eye ifa ni nwon se fun awon enia li odan nilu Eko, gbogbo ilu ni o ta asia si fi ki won kabo, E kabo o ero one.

Awon igbimo Lagos Town Council lo ta asia kakiri ilu Eko lati fi ki awon Alagbara na si. Alajyeluwa Adele keji, oba ilu Eko li o lo pade won ni gbalasa Odan lati ki won kabo, o si gba owo lowo enikokan won.

## Q'ola Akintola Be Ilu Iragbiji Wo

**Iragbiji** Irohin ti bere si ino kakiri ilu nigbati a gbo wipe Ogbeni Qlola S. L. Akintola mbo lati wo be awon omo egbe Afenifere ti o mbe nilu na wo, ati lati gba nu wa ni awon elegbe-egbe ti omura fun dide re. Ope awon enia ti o ti ngbo irohin re nfe lati ri eni nle yi ti o si je omo ile Yoruba, epo eyin si nfe gbo oro enu re pelu.

Lojo ti o ni lati de Iragbiji gbogbo awon gbajumo ati awon iyaloja ni gbadun pelu Ifon, ilu ati ijo ti lo pade re lehin odi. Oba Iragbiji Ajasnoke keji ati awon ijoye re ti tote joko de alejo na ninu Afin oba, awon oreti diedie re.

Ko pe pupo lehin eyi ni Alejo na de, ero gbogbo awon omo Egbe Afenifere to mbe ninu na fi pe samu samu. Awon nti ko si ninu egbe yi tele lojo na ni nwon ko iowo tese won sinu egbe na. Iyi nla le je fun enikeni lojo na ti Qlola Akintola ba gba owo lodo re.

O soro ti o wu gbogbo enia lori lojo na, o si fi asiri ise ti Egbe Afenifere nse han, ati Oba ati Ijoye ati gbogbo ara ilu lo ko tapa tese won sinu egbe Afenifere (A. G.)

## Abeokuta Ati Agbegbe Re

Iye enia ti o mbe nigboro ilu Abeokuta apapo Egba Alake, Gbagura, Oke Ona ati Ago Owu je 84,451.

Tesgn Agbado ati agbegbe re je 12,425

Ase ati agbegbe re je 28,310.

| | | |
|---|---|---|
| Ifo | „ „ „ | 35,743 |
| Ilugun | „ „ „ | 19,375 |
| Imala | „ „ „ | 10,807 |
| Ipaga | „ „ „ | 10,323 |
| Itori | „ „ „ | 23,551 |
| Mokoloki | „ „ „ | 22,375 |
| Oba | „ „ „ | 25,541 |
| Opeji | „ „ „ | 10,730 |
| Osiele | „ „ „ | 29,061 |
| Otta | „ „ „ | 39,023 |
| Owode | „ „ „ | 32,049 |
| Ado Egun | „ „ „ | 31,769. |
| Igbesa | „ „ „ | 14,890 |
| Ajilete | „ „ „ | 11,457 |
| Oke Odan | „ „ „ | 6,333 |

Apapo gbogbo Egba, 393,800

Apapo gbogbo Egbado 236,030

Apapo gbogbo enia to mbe ni agbegbe ilu Abeokuta, je 629,830.

**REDIFFUSION**

LISTENERS

**E**NJOY
**D**AILY
**I**NTEREST AND ENTERTAINMENT
**F**ROM 6 A.M TILL 11 P.M
**U**NRIVALLED
**S**ERVICE ALREADY
**I**NSTALLED IN
**O**NLY 2 YEARS IN NEARLY 40,000
**N**IGERIAN WESTERN REGION HOMES

Building for HIS future



THE UNITED AFRICA COMPANY looks to the future. It is using the money it makes through trade with West Africa to develop commercial and industrial operations in West Africa. During the last five years it has put back into West African enterprises, in the form of buildings, roads, plant and machinery, more than £10 millions. In this way The United Africa Company is enriching West Africa's economy, raising her standard of living, and providing innumerable openings in industry or commerce for tomorrow's citizens.

**THE UNITED AFRICA COMPANY LTD**

Printed & Published by The Union Printing and Publishing Company, 65 Kosoko Street P O Box 467 Lagos, Phone 23370